# Ẹ bẹru Ọlọhun Oluwa yin, ẹ ki irun wakati marun-un yin, ẹ gba awẹ osu yin, ẹ yọ saka awọn dukia yin, ẹ tẹle adari àlámọ̀rí yin ẹ maa wọ alujanna Olúwa yín

Lati ọdọ Abu Umaamah- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pe: Mo gbọ́ ti ojisẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n sẹ khutubah ni hajj idagbere, o sọ pe: "Ẹ bẹru Ọlọhun Oluwa yin, ẹ ki irun wakati marun-un yin, ẹ gba awẹ osu yin, ẹ yọ saka awọn dukia yin, ẹ tẹle adari àlámọ̀rí yin ẹ maa wọ alujanna Olúwa yín".
[O ni alaafia] [Tirmiziy ati Ahmad ni wọ́n gba a wa]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sẹ khutubah ni ọjọ 'Arafah, ni hajj idagbere, ni ọdun kẹwàá ninu hijira, wọn sọ ọ ni orúkọ yẹn; nitori pe Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- dagbere fun awọn eniyan nibẹ, O pa awọn eniyan patapata láṣẹ lati bẹru Oluwa wọn pẹlu mimu awọn àṣẹ Rẹ ṣẹ ati jijina si awọn ẹkọ̀ Rẹ. Pe ki wọn maa ki awọn irun maraarun-un ti Ọlọhun- Alagbara ti O gbọnngbọn- sẹ wọn ni ọran-anyan ni ọsan ati alẹ. Pe ki wọn maa gba awẹ osu Ramadan. Pe ki wọn maa yọ saka awọn dukia fun awọn ti wọn lẹtọọ si i ki wọn si ma sẹ ahun pẹlu rẹ. Pe ki wọn maa tẹle awọn ti Ọlọhun fi sẹ adari le wọn lori, yàtọ̀ si ibi ṣiṣẹ Ọlọhun, Ẹni ti o ba sẹ awọn nnkan ti a dárúkọ yìí, ẹsan rẹ ni wiwọ alujanna.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3520